Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p.111-126 | jan./ jun.2025.

# Ìṣàmúlò Eré àti Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fún Àyípadà Àwùjọ àti Àtúnṣe ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà

# Exploring the Use of Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Performance and Poetry in Fostering Social Change and Reconstruction in Nigeria

**Ilufoye Fawọle Òjó, PhD** *
ORCID iD https://orcid.org/0009-0004-5393-5915

**ÀṢAMỌ̀ (yoruba)**
Ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ eré ẹ̀fẹ̀ tí àwọn Yorùbá máa ń ṣe lọ́dọọdún pàápàá jù lọ àwùjọ ìran Yorùbá tí wọ́n wà ní ilẹ̀ Olómìnira Bìnì ní agbègbè Kétu, Sábẹ̀ẹ́, Ìpòbẹ́, Nàgó, Ọ̀họ̀rí, Ìdànín àti àwọn àwùjọ mìíràn ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà bí Ẹ̀gbádò, Ìmẹ̀kọ, Ìgbógilá, Ìlaròó ní ìpínlẹ̀ Ògùn. Ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tún máa ń wáyé ní àwọn ìlú bí i Ìjìó, Ìgànná, Igbó-ọrà àti ní agbègbè Ìbàràpá méjèèje ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́. Eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tún máa ń wáyé ní ìsàlẹ̀ Èkó, ní ìpínlẹ̀ Èkó. Tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀, pàtàkì eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ni láti fi bu ọlá, iyì àti ẹ̀yẹ fún àwọn alágbára obìnrin àwùjọ. Bákan náà ni wọ́n tún ń ṣe eré yìí láti fi ṣe àpọ́nlé fún àwọn Ìyàmi, àwọn Àgbà tàbí Àjẹ́ láti lè fi wá ojú rere wọn tàbí yẹ́ wọn sí kí wọ́n baà lè fi gbogbo agbára tí ó bá wà ní ìkáwọ́ wọn láti lè fi tún àwùjọ ṣe. Ní báyìí, ọpọ́n orin àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti sún, ó ti kúrò ní àwùjọ àwọn Ìyàmi, ó ti di èyí tí à ń lò níbi onírúurú ayẹyẹ gbogbo. Onírúurú orin ni àwọn ẹlẹ́fẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń kọ, oríṣìíríṣìí ewì ni wọ́n sì máa ń ké lásìkò tí wọ́n bá ń ṣe eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Ewì àti orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kún fún àfihàn ọ̀rọ̀ òṣèlú, ètò ọrọ̀-ajé, ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn, ẹ̀fẹ̀ ní ọlọ́kan-ò-jọ̀kan, èébú àti ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí tí ó jẹ mọ́ àwùjọ. Ohun tí iṣẹ́ yìí dá lé gan-an ni ṣíṣe àfihàn ipa tí orin àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń kó, láti lè mú àyípadà tó dúróore, bá orílẹ̀-èdè. Àkíyèsí fi hàn pé onírúurú ìwà àìtọ́ tí Yorùbá lòdì sí, àti àwọn ìwà tí ò ṣe é mú yangàn fún àyípadà orílẹ̀-èdè sí rere ni orin àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń tẹpẹlẹ mọ́. Èyí sì ni iṣẹ́ ìwádìí yìí tún gbé yẹ̀wò. Iṣẹ́ yìí wá dá a lábàá, ó sì tún fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé bí a bá lè tẹ́wọ́ gba àmúlò orin àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ nínú ètò ìṣèjọba orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, tí a sì ń lò ó níbi ayẹyẹ gbogbo, ó dájú pé àyípadà rere yóò bá ètò òṣèlú, ètò ọrọ̀-ajé àti ọ̀rọ̀ amúlùúdùn ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

**KÓKÓ-Ọ̀RỌ̀**
Gẹ̀lẹ̀dẹ́, Ìṣèré, Ewì, Àyípadà Àwùjọ, Àtúnṣe, Àṣà Yorùbá.

**ABSTRACT**
Gẹ̀lẹ̀dẹ́, a traditional Yorùbá satirical performance art form is celebrated yearly particularly among the Yoruba descendants of Benin Republic in Kétu, Sábẹ̀ẹ́, Ìpòbẹ́, Nàgó, Ọ̀họ̀rí, Ìdànín and several other communities in Nigeria like Ẹ̀gbádò, Ìmẹ̀kọ, Ìgbógilá, Ilaro in Ògùn State, Nigeria. Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ritual performance is also prominent in some communities like Ìjìó, Ìgànná, Igbó-ọrà and among the seven communities in Ọ̀yọ́ and Lagos states of Nigeria respectively. From time immemorial, Gẹ̀lẹ̀dẹ́ performance was majorly centred on the celebration of powerful women, witches (àwọn àjẹ́, àwọn àgbà or àwọn ìyàmi) in the society so as to receive their favour and in turn explore all the powers at their disposal to reconstruct the society. Today, Gẹ̀lẹ̀dẹ́ performances have been reformed, repackaged and utilized as catalyst for social change apart from utilizing it to placate the powerful women only. Findings have shown that Gẹ̀lẹ̀dẹ́ performances and its poetry are full of

* Department of Yorùbá, Adéyẹmí Federal University of Education, Oǹdó. E-mail: ilufoyeojo@gmail.com

entertainment, showcasing political, economic, religious, social commentary, critique, philosophical, satirical and ethical values. Therefore, this paper examines the ways in which Gẹ̀lẹ̀dẹ́ performances and poetry have been utilized as a catalyst for social change and reconstruction, through a critical analysis of Gẹ̀lẹ̀dẹ́ texts, performances, and interviews with the practitioners, this paper reveals the art form's potential to challenge dominant narratives, promote social justice, economic development, political system, religious harmony; and foster community empowerment. By exploring the intersections of art, culture, and social change, this research demonstrates the significance of Gẹ̀lẹ̀dẹ́ as a tool for reconstructing and imagining a more equitable Nigeria.

**KEYWORDS**
Gẹ̀lẹ̀dẹ́, Performance Art, Poetry, Social Change, Reconstruction, Yorùbá Culture.

**Ìfáárà**

Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ ẹ̀yà eré ajẹméwì àti ajẹmáwòrán tí ó ń fi ètò ìgbé-ayé àwùjọ tí ó ti ń wáyé hàn. Eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tún jẹ mọ́ ewì ajẹmétùtù fún ìtùbà-tùṣẹ àwùjọ. A máa ń fi eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ṣe àpọ́nlé àwọn "Ìyá Wa", "Ìyá Ńlá", "Ìyàmi" àwọn àjẹ́ tàbí àwọn àgbà láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀, ṣùgbọ́n ní òde-òní, àwọn àkóónú eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti kọjá kí a máa fi bu ọlá, iyì àti ẹ̀yẹ fún àwọn "Ìyá wa" nìkan. Yàtọ̀ sí pé à ń fi eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ṣe ìdárayá, ó tún wà fún ìkìlọ̀, ìgbani-nímọ̀ràn, ìtani-lólobó àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, ìgbé àṣà láruge, ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti àjọṣepọ̀ láàrin takọ tabo.

Bákan náà, eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti kọjá àwùjọ àti agbègbè bí i Kétu, Sábẹ̀ẹ́, Ìpòbẹ́, Nàgó, Ọ̀họ̀rí Ìdànín àti àwọn àwùjọ mìíràn ní orílẹ̀-èdè olómìnira Bìnì. Eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sì ti tún kọjá Ẹ̀gbádò, Ìmẹ̀kọ, Igbógilá, Ìlaròó àti àwọn àwùjọ mìíràn ní ìpínlẹ̀ Ògùn. Bákan náà, Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti tún kọjá àwùjọ tí ó ti máa ń wáyé ní Ìjìó, Ìgànná, Igbó-ọrà àti ní agbègbè Ìbàràpá méjèèje ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ àti Ìsàlẹ̀ Èkó. Ìtànkálẹ̀ eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti kọjá lọ sí òkè-òkun sí àwọn agbègbè kan ní Latin America, Europe, Australia àti ní gbogbo ibi tí àwọn ọmọ ilẹ̀ Adúláwọ̀ tẹ̀dó sí lápapọ̀. Orin, ewì àti ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti tún kọjá eré tí à ń ṣe lábẹ́lé nìkan, níbi tí àwọn òṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ yóò ti kóra wọn jọ pọ̀ ní gbàgede ọjà, gbọ̀ngàn ńlá ìlú, ní abẹ́ igi tàbí ọdán ńlá tí abẹ́ rẹ̀ fẹ̀ dáadáa láti ṣe àfihàn onírúurú ohun ajẹmáwùjọ, ètùtù àti ẹ̀sìn àwọn ènìyàn àwùjọ (Klein, 2007). Eré yìí ti gbòòrò débi pé ó ń tani-lólobó onírúurú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, ó sì ń mú ìbáṣepọ̀ tó gbòòrò bá tọkùnrin tobìnrin láàrin àwùjọ (Wiredu, 2000). Iṣẹ́ àwọn ẹgbẹ́ ajógẹ̀lẹ̀dẹ́ tàbí òṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ni láti máa wá ìbágbépọ̀ àlàáfíà sí àarin ọmọ ènìyàn àti àwọn àjẹ́ (Lawal, 1996). Yorùbá gbà pé àwọn obìnrin lágbára, wọ́n sì mọ àṣírí ayé. Wọ́n ní agbára láti lè bí ọmọ ènìyàn sílé ayé, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n sì tún lè padà mú un kúrò láyé. Ní ìdí èyí, Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ ọ̀nà kan tí à ń gbà bu ọlá fún obìnrin. Ó sì tún jẹ́ ọ̀nà tí à ń gbà fi ìmọ̀rírì wọn hàn nípa ìdàgbàsókè tí wọ́n ń mú bá àwùjọ àti ipa tí wọ́n ń kó nínú ètò àwùjọ.

Ọ̀pọ̀ iṣẹ́ ló ti wà lórí Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Iṣẹ́ takuntakun ni àwọn ènìyàn pàápàá àwọn onímọ̀ ti ṣe nípa ẹ̀fẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn rárá. Díẹ̀ lára àwọn onímọ̀ ìṣáájú bí Beier (1958) ṣàlàyé pé eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ wà fún ìjọsìn àwọn "Ìyá wa". Mulero (1970) sọ pé Ẹ̀fẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń bu ẹnu àtẹ́ lu àwọn ìwà ìbàjẹ́ ọmọ ènìyàn láwùjọ. Iṣẹ́ ìwádìí Fálẹ́yẹ (2009) fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé eré àti ìpohùn Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń kó ipa pàtàkì nínú mímú àmúgbòòrò bá àṣà àti ìṣe Yorùbá, ó sì yẹ kí àwùjọ Yorùbá gbárùkù tì í. Ohun tí a ṣe àkíyèsí nípa ìwádìí lórí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ni pé iṣẹ́ àwọn onímọ̀ kò tí ì rinlẹ̀ tó lórí bí eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti ewì rẹ̀ ṣe lè mú àyípadà rere bá orílẹ̀-èdè. Àlàfo tí ó ṣí sílẹ̀ yìí ni iṣẹ́ yìí fẹ́ dí. Ohun tí a fẹ́ ṣe nínú iṣẹ́ yìí gan-an ni láti wo ọ̀nà tí a lè gbà ṣe àmúlò eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ láti lè tún àwùjọ wa ṣe. Àyípadà tí ó dé bá ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lóde-òní ti jẹ́ kí á mọ̀ pé kì í ṣe láti fi ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ júbà, ki oríkì, ṣe ìwúre, sọ ìtàn, ṣe ẹ̀fẹ̀ nípa gbígbé oríyìn fún oníwà rere tàbí tàbùkù oníṣẹ́ ibi lọ́nà ẹ̀rọ nìkan ni a lè fi ṣe, bí kò ṣe láti fi yí àwùjọ padà sí rere. Ẹ̀wẹ̀, àwọn ìwà ọmọlúàbí tí ó ń jẹ yọ nínú eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ kí á mọ̀ pé ipa pàtàkì ni ó ń kó gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn kan, tí ó ń mú

ìgbé-ayé àlàáfíà àti ìrọ̀rùn bá àwùjọ. Nítorí náà, ọ̀nà tí a lè gbà láti fi ìṣèré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ yí orílẹ̀-èdè padà sí rere ni a fẹ́ gbé yẹ̀ wò nínú iṣẹ́ yìí.

Ọ̀nà ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò àti ìtúpalẹ̀ ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tí a ṣe àdàkọ wọn sílẹ̀ ni a gbà ṣe iṣẹ́ yìí. Ní àkọ́kọ́, a gba ewì àti orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sílẹ̀ láti ẹnu àwọn ọ̀kọrin àti òṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìjìó, Sábẹ̀ẹ̀, Ìgànná àti Ìpòbẹ́. A tún ṣe àmúlò fọ́nrán orin àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tí ó wà ní ìkáwọ́ wa. Ẹ̀ka-èdè àwọn òṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ wọ̀nyí ni wọ́n fi kọ orin wọn, ṣùgbọ́n a ṣe àdàkọ àwo orin wọ̀nyí, a sì tú u sí olórí ẹ̀ka-èdè Yorùbá, kí òye ìtumọ̀ tí ó ní ó lè ba à yé gbogbo ẹni tí ó bá ka iṣẹ́ ìwádìí yìí yékéyéké. Àyẹ̀wò iṣẹ́ àwọn ọ̀mọ̀ràn ìṣáájú lórí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ náà ràn wá lọ́wọ́ púpọ̀ láti lè ṣe iṣẹ́ yìí ní àṣeyọrí.

### Aáyan Àwọn Ọ̀mọ̀ràn lórí Gẹ̀lẹ̀dẹ́

Àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ aláwọ̀ funfun àti ti aláwọ̀ dúdú ló ti ṣe iṣẹ́ ribiribi lórí orírun, ìdàgbàsókè, orin, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò, gàrétà àti ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí sì ni wọ́n jẹ́ àtẹ̀gùn fún iṣẹ́ ìwádìí yìí. Johnson (1921) sọ fún wa pé Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ ẹ̀dá ènìyàn tí ó gbé gàrétà tí a gbẹ́ pẹ̀lú igi lọ́nà àrà ọ̀tọ̀ tí arugi gbé borí. Gàrétà yìí sì máa ń ṣe àfihàn àwòrán ọkùnrin tàbí obìnrin tí ó ní ìlà lẹ́rẹ̀kẹ́. Gàrétà yìí tún lè ní àwòrán ẹranko bí i ejò, akíka, ẹkùn, ológìnní tàbí ẹyẹ lára. Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń ṣe ọ̀ṣọ́ tí ó rẹwà sí ara. Ìgbésẹ̀ ijó rẹ̀ sì máa ń bá ìwọ́hùn ìlù àti orin mu dáradára. Beier (1958) ṣàlàyé pé ìdásílẹ̀ eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ wáyé láti ọwọ́ àwọn obìnrin. Ìdí ni pé ní ìgbà láéláé, àwọn obìnrin ní agbára ìṣèlú àwùjọ lọ́wọ́ púpọ̀ ju ti ayé òde-òní lọ. Èrò Beier yìí kò fẹ́rẹ̀ yàtọ̀ sí iṣẹ́ Ìbítòkun (1993:38) nígbà tí ó ṣàlàyé pé:

> *Women were at the centre of Egúngún cult in the past but it was as a result of their excesses that men hijacked it from them. As a retaliatory and reprisal attack, women formed Gẹ̀lẹ̀dẹ́ cult which is exclusively controlled by women till date.*
>
> Àwọn obìnrin ni wọ́n ti fígbà kan rí wà ní ààrin gbùngbùn awo Egúngún ṣùgbọ́n nípasẹ̀ àṣejù wọn ni ó mú kí àwọn ọkùnrin ó gbà á mọ́ wọn lọ́wọ́. Gbígba ẹ̀san àti ṣíṣe ìkọlù padà ló mú kí àwọn obìnrin ó dá awo Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sílẹ̀, tí ó sì jẹ́ pé àwọn náà ni wọ́n ń ṣe agbátẹ́rù àti ìṣàkóso rẹ̀ títí di òní.

Àyọlò òkè yìí ni ó fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé awo obìnrin ni Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́. Àwọn sì ni agbátẹ́rù rẹ̀. Alábàáṣe àti olùrànlọ́wọ́ nípa ìlù lílù, ẹkú Gẹ̀lẹ̀dẹ́ rírù láti fi máa yẹ́ àwọn obìnrin sí nìkan ni awọn ọkùnrin wà fún. Speed (1968) náà ṣiṣẹ́ lórí fíìmù ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìjìó. Happer (1970) ṣiṣẹ́ takuntakun lórí ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ nígbà tí Kerchache (1973) ní tirẹ̀ ṣiṣẹ́ lórí àkásílẹ̀ ayẹyẹ eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní orílẹ̀-èdè olómìnira Bìnì níbi tí ó ti ya àwòrán Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní èròǹgbà kíkó wọn pamọ́ sí abẹ́ ààbò. Yàtọ̀ sí àwọn wọ̀nyí, Bernolles (1973) ṣe ìtúpalẹ̀ mótíìfù oríṣìí gàrétà Gẹ̀lẹ̀dẹ́ méjì ní Sábẹ̀ẹ̀. Aṣíwájú (1975, 1976) ṣe àyẹ̀wò pàtàkì ìmọ̀-ìtàn nínú orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ nígbà tí Ọlábímtán (1970, 1972), Fáyọmí (1982), Ìbítókun (1981, 1987, 1993) ṣiṣẹ́ lórí ẹ̀kọ́ nípa ètùtù, ìmọ̀ ẹ̀dá-èdè àti abala ajẹmọ́ eré-oníṣe nínú eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ẹ̀gbádò-Kétu. Lawal (1998) gbìyànjú láti ṣiṣẹ́ lórí ipa àwùjọ lórí bí a ti ṣe ń lo èdè nínú eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Thompson (1978) fojú wo ìmọ̀ ẹwà nínú ijó àti aṣọ-eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Drewal àti Drewal (1974a, 1974b, 1975, 1983) àti Lawal (1978) ti ṣe iṣẹ́ ìwádìí tó gbòòrò nípa iṣẹ́-ọnà Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Àwọn onímọ̀ wọ̀nyí ti fi Gẹ̀lẹ̀dẹ́ hàn gẹ́gẹ́ bí àmì agbára obìnrin láwùjọ Yorùbá, ṣùgbọ́n wọn kò ṣe ìtúpalẹ̀ eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fún àyípadà orílẹ̀-èdè. Ọlátúnjí àti Koenane (2016) náà ṣiṣẹ́ lórí àròjinlẹ̀ orírun àti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò nípa ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ nígbà tí Lawal, Irhue àti Aliu (2021) ṣàlàyé nípa ìṣèré ẹ̀fẹ̀ àti Gẹ̀lẹ̀dẹ́, ìbẹ̀rẹ̀ eré ẹ̀fẹ̀, àrà dídá nínú eré-ẹ̀fẹ̀ ní àwùjọ Yorùbá òde-òní ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà.

Òjó (2016, 2017, 2020, 2021, 2024) ṣe àgbéyẹ̀wò iṣẹ́-ọnà ajẹmẹ́wì àti ajẹmáwòrán, ìtúpalẹ̀ ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò, ìṣàfihàn àwọn ọ̀rọ̀ tí ó ń lọ láàrin àwùjọ àti àfihàn agbára obìnrin nínú iṣẹ́-ọnà ajẹmẹ́wì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ láwùjọ Yorùbá àti Willis (2018) sọ̀rọ̀ nípa orírun àti ìtàn Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Ọlọ́runtó (2004) ṣe àfihàn Gẹ̀lẹ̀dẹ́ gẹ́gẹ́ bí eré oníjó tí arugi Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń ṣe ní àsìkò ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tàbí ní gbogbo ibi tí eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ bá ti ń wáyé ní àwùjọ.

Fálẹ́yẹ (2009) ṣàlàyé pé ìpohùn eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú eré-oníṣe àbáláyé tí ó gbajúgbajà láàrin àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí ó wà ní agbègbè Kétu, Ẹ̀gbádò, Sábẹ̀ẹ́ àti Ọ̀họ̀rí. Orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ yìí sì ń kó ipa pàtàkì nínú àtunṣé àwùjọ Yorùbá (Tìámíyù àti Ọlátáyọ̀, 2014). Bí a bá wo èrò àwọn onímọ̀ ìṣáájú nípa ìṣẹ̀ré Gẹ̀lẹ̀dẹ́, a ó rí i pé èrò wọn kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí ara wọn. Èrò Beier (1958), Harper (1970) àti Aṣíwájú (1975) kò yàtọ̀ sí ti Drewal àti Drewal (1983) àti Òjó (2016, 2017, 2020, 2021, 2024) pé a ṣe eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ láti ṣe àyẹ́sí àti àpọ́nlé fún àwọn obìnrin alágbára, ó ń fi agbára àṣẹ ìbí tí Olódùmarè gbé lé wọn lọ́wọ́ hàn, bẹ́ẹ̀ ni ó sì tún wà fún ìjọsìn fún àwọn Ìyàmi. Ní èrò tiwa, Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ eré-oníṣe ajẹmẹ́wì àti ajẹmáwòrán, eré-oníṣe ajemétùtù àti ìdárayá tí a fi ń ṣe àpọ́nlé fún àwọn alágbára obìnrin. Eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tún wà fún ìkìlọ̀ ìwà, ìgbani-nímọ̀ràn àti ìtanilólobó àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ bẹ́ẹ̀ ni ó tún ń fi ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá hàn. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìwà ọmọlúàbí tí ó ṣe é mú yangàn ló kún inú eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fọ́fọ́.

**Orírun àti Ìbẹ̀rẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́**

Onírúurú ìtàn ìwáṣẹ̀ àti ìtàn àtẹnudẹ́nu ni a ti gbọ́ nípa orírun àti ìbẹ̀rẹ̀ eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Olóyè Erínfọlámí tí ó jẹ́ abọ̀rẹ̀ àti olórí awo Ẹ̀fẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní ìlú Èkó sọ pé Gẹ̀lẹ̀dẹ́ náà ni à ń pè ní Àshẹ (Àṣẹ), èyí tí ó dúró fún àmì "Ìyá Ńlá". Ẹ̀mí àìrí tí ó bí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sáyé ni àwọn baba-ńlá wọn mú wá láti odò sí ìsàlẹ̀ Èkó àti agbègbè rẹ̀ ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún sẹ́yìn. Òrìṣà odò gẹ́gẹ́ bí Olúwẹri (abo òrìṣà) ni. Ó jẹ́ òrìṣà alábiyamọ. Láti Kétu ni ó ti wá, láti wá fi ara han àwọn ará ìsàlẹ̀ Èkó. Láti Kétu ni Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti tàn dé ìsàlẹ̀ Èkó nítorí ètò ọrọ̀-ajé nípa kátàkárà, pàápàá òwò ẹja ṣíṣe. Ìtàn ìwáṣẹ̀ nípa Gẹ̀lẹ̀dẹ́ yìí kò fí bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí ìtàn èyí tí à ń kà nínú Ìbítókun (1993) tí ó sọ pé láti Ìlobí tí ó sún mọ́ etí òkun (odò) ni Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti bẹ̀rẹ̀. Ìlobí jẹ́ ìlú kan tí ó sún mọ́ Kétu ní orílẹ̀-èdè Olómìnira Bìnì. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń ki Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní:

*Ará Ìlobí afidẹ gbàngbà jó*
*Ṣaworo idẹ gbàngbà tí ó wà lẹ́sẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ló máa ń mú ijó rẹ̀ rẹwà.*

Oríṣìí ìtàn mìíràn tún sọ pé ẹnìkan sùn ó sì lá àlá. Láti ojú oorun níbi tí ó ti ń lá àlá ni wọ́n ti kó ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́, ìwọ́hùn orin rẹ̀, aṣọ-eré àti gàrétà Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fún ẹni náà, pé kí ó máa fi jó ijó àrà. Nígbà tí ó jí ni ó bá di ọmọlẹ́yìn Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Àhesọ ìtàn gbáà ni èyí nítorí pé kò sí bí a ti ṣe lè fi ẹsẹ̀ èyí múlẹ̀ (Ìbítókun, 1993). Àhesọ ìtàn mìíràn tí Ìbítókun (1993), Drewal àti Drewal (1983) tún sọ ni pé Gẹ̀lẹ̀dẹ́ bẹ̀rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ àwọn ìbejì kan tí wọ́n wá láti ìdílé ọba ní ìlú Kétu. Orúkọ àwọn ìbejì yìí ni Àkán àti Adébìyá. Àkán àti Adébìyá dìjọ ń du ipò ọba mọ́ ara wọn lọ́wọ́. Wàhálà oyè dídù yìí ló mú Adébìyá sá kúrò ní Kétu. Gàrétà Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ni Adébìyá gbé sójú padà bọ̀ wá sí ilé. Èyí ló mú kí ẹ̀rù ba Àkán, ó sì sá kúrò lórí oyè. Nígbẹ̀yìn, wọ́n parí ìjà, Adébìyá gun orí oyè ọba Kétu. Níbí sì ni ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti bẹ̀rẹ̀. Irú ìtàn àhesọ yìí kò jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà rárá nítorí pé kò fìdí òtítọ́ ìtàn múlẹ̀. Ìbítókun (1993) tẹ̀ ṣíwájú nínú ìtàn Gẹ̀lẹ̀dẹ́ pé Gẹ̀lẹ̀dẹ́ bẹ̀rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ Mélée (ìtàn àwọn tọkọ taya) tí wọn kò rí ọmọ bí. Ìtàn yìí sọ mọ́ ìlú Ìlobí ní agbègbè Kétu.

Ìlobí túmọ̀ sí "ibi tí ó lóyin nínú tí ọmọ bíbí sì ti rọrùn". Àwọn tọkọ taya yìí gba oko aláwo lọ ní Kétu láti lọ yẹ ìgbé ayé wọn wò láti mọ ìdí tí wọn kò fi rí ọmọ bí. Ifá ní kí wọn ó jìnà sí ìlú tí a gbé bí wọn. Ó ní kí wọ́n gbé Gàrétà, kí wọ́n sì rọ ṣaworo/gbọnngúdú kí ọkọ obìnrin yìí sì so wọ́n mọ́ ẹsẹ̀ rẹ̀ kí ó sì máa jó káàkiri láti lè fi máa wá ojú rere àwọn òrìṣà àti "ayé". Àwọn tọkọ taya yìí rúbọ, ẹbọ sì dà, wọ́n sì di ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọlọ́mọ láyé. Láti ibi ijó jíjó pẹ̀lú gàrétà gbígbé borí pẹ̀lú ṣaworo idẹ lẹ́sẹ̀ ni eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti bẹ̀rẹ̀ ní Ìlobí. Ìtàn yìí fìdí múlẹ̀

púpọ̀ nínú ìgbé-ayé àti ìgbàgbọ́ àwọn Ìlobí. Títí di òní ni àwọn ará Ìlobí tún máa ń rántí àwọn tọkọ taya tí wọ́n ya àgàn, ṣùgbọ́n tí wọ́n padà di ọlọ́mọ yìí. Ìdí nìyí tí wọ́n fi so Gẹ̀lẹ̀dẹ́ mọ́ ètò ìbímọ ní àwùjọ wọn mọ́ awo abiyamọ àti awo ìbejì. Èyí ló sì fi awo Gẹ̀lẹ̀dẹ́ hàn gẹ́gẹ́ bí awo abiyamọ. Nítorí náà, onírúurú ìtàn ìwáṣẹ̀, ìtàn àhesọ tàbí àròbájọ yòówù kí a lè sọ nípa bí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ṣe bẹ̀rẹ̀, ohun tí ó dájú ni pé iṣẹ́-ọnà Ìlobí ní Kétu ni ó jẹ́. Àyọlò ìlà oríkì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kan fi ìdí èyí múlẹ̀ báyìí pé:

*Ìhà Ìlobí ni mo ti ń bọ̀*
*Ẹ kí oníjó káàbọ̀*
*Ẹ ṣe awo ní báríkà kú ijó*
*Èjó iná ni mí*
*N kò ṣe é fi sábẹ́ aṣọ*

Àyọlò òkè yìí jẹ́ kí á gbà pé Ìlobí ní Kétu ni ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti bẹ̀rẹ̀ kí ó tó wá di pé àyípadà dé bá a tí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í tàn káàkiri agbègbè Kétu, Ìpòbẹ́, Ìdànín, Sábẹ̀ẹ̀ ní orílẹ̀-èdè Olómìnira Bìnì àti àwọn kan ní ìpínlẹ̀ Ògùn bí Ìlaròó, Abẹ́òkúta, Ìpókiá, Igbógilá àti Ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́ bí Ìjìó, Igbó-ọrà àti Ìgànná.

Àlàbá (1992) ṣàlàyé pé Ẹ̀fẹ̀ jẹ́ orúkọ tàbí àlàjẹ́ kan pàtàkì tí àwàdà ní. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ẹ̀fẹ̀ yàtọ̀ sí àwàdà síbẹ̀ ọmọ ìyá kan náà ni a lè pè wọ́n. Àlàbá tẹ̀ ṣíwájú pé Olóyè Fágbèmí Àjànàkú, Àràbà Èkó nígbà kan rí ni ó kọ́kọ́ sọ ọ́, tí òun sì fi etí ara òun gbọ́ ọ lórí rédíò ní déédéé agogo mẹ́jọ ààbọ̀ alẹ́ ọjọ́ kéje oṣù kìn-ín-ní ọdún 1977 pé ọkùnrin apani-lẹ́rìn-ín ni Ẹ̀fẹ̀ ń ṣe. Alẹ́ ni ó sáábà máa ń ṣeré fún àwọn ènìyàn. Ọkùnrin yìí jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ọmọ mẹ́ta tí Yemọja bí fún Olúwẹri. Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti Tètèdé ni orúkọ àwọn méjèèjì yòókù. Nígbà tí wọ́n dàgbà, wọ́n di ọlọgbọ́n tí Ọ̀rúnmìlà kọ́ ní ọgbọ́n láti máa bá àwọn ènìyàn lé ibi jìnnà kúrò ní àwùjọ wọn. Láti inú ẹsẹ Ifá ni ìtàn ìwáṣẹ̀ yìí ti jẹ jáde. Èyí sì jẹ́ kí á tún lè gbà á gbọ́ pé láti inú ẹsẹ Ifá ni ọ̀rọ̀ nípa Gẹ̀lẹ̀dẹ́, Ẹ̀fẹ̀ àti Tètèdé ti jáde. Bí a bá sì wò ó dáadáa, a ó rí i pé Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń ṣe ẹ̀fẹ̀, ó sì tún máa ń ṣe àwàdà tí ó máa ń pa ni lẹ́rìn-ín.

Ní èrò ti Lawal (1996), láti ọ̀dọ̀ Yemọja ni Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti bẹ̀rẹ̀. Ìtàn tí Lawal pa náà kò fẹ́rẹ̀ yàtọ̀ sí ti Àlàbá (1992). Lawal (1996:39) sọ pé nínú ẹsẹ odù Ifá Ìwòrì méjì ni a ti gbà pé Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti bẹ̀rẹ̀. Ó ní:

> *An ẹsẹ Ifá explains the origins of Gẹ̀lẹ̀dẹ́ as beginning with Yemọjas, the mother of all the Òrìṣà and all living things.*
>
> Ẹsẹ Ifá kan ni ó ṣàlàyé nípa bí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ṣe bẹ̀rẹ̀ láti ipasẹ̀ Yemọja tí ó jẹ́ ìyá gbogbo àwọn òrìṣà àti àwọn nǹkan ẹlẹ́mìí yòókù. Lawal (1996:39)

Àyọlò òkè yìí tún là wá lóye nípa orírun eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ yìí láwùjọ. Ìtàn tí Lawal pa yìí tẹ̀ síwájú pé Yemọja kò rí ọmọ bí, ó sì ń ṣe àwáàrí, èyí ló mú un lọ sí ọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmìlà láti yẹ òun lọ́wọ́ kan ìbò wó. Ifá ní kí ó rúbọ, kí ó sì gbé àwòrán gàrétà bojú, kí ó sì bẹ̀rẹ̀ sí í jó káàkiri pẹ̀lú ṣaworo onídẹ lẹ́sẹ̀ rẹ̀. Nígbẹ̀yìn, Yemọja finú ṣoyún ó sì fẹ̀yìn gbé ọmọ pọ̀n. Ọmọkùnrin ni ó kọ́kọ́ bí, tí ìnagijẹ rẹ̀ ń jẹ́ "Ẹ̀fẹ̀". Ọmọbìnrin ni ó bí ṣìkejì. Orúkọ rẹ̀ á máa jẹ́ "Gẹ̀lẹ̀dẹ́". Ìdí tí a fi pè é ní Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ni pé ó sanra púpọ̀, ó sì tún fẹ́ràn ijó bí ìyá rẹ̀ pẹ̀lú. Lẹ́yìn tí "Ẹ̀fẹ̀" gbéyàwó tí "Gẹ̀lẹ̀dẹ́" náà sì lọ́kọ tán ni àwọn méjèèjì kò ti rí ọmọ bí.

Ọ̀rúnmìlà wá gbà wọ́n níyànjú láti rú irú ẹbọ tí ìyá wọn rú ní ọjọ́sí kí wọ́n baà lè di ọlọ́mọ láyé. Wọ́n gbọ́, wọ́n sì rúbọ. Ẹbọ sì dà. Báyìí ni àwọn méjèèjì ti ṣe bẹ̀rẹ̀ sí í bímọ nítorí ẹbọ tí wọ́n rú lọ́jọ́sí. Ẹbọ àti ètùtù tí wọ́n ṣe yìí ni ìdàgbàsókè dé bá tí ó sì di ohun tí a

mọ̀ sí ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tí àwọn ìran, ọmọ Ẹ̀fẹ̀ àti Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sì ń tàn kálẹ̀ káàkiri títí di òde-òní. Bí a bá tẹ̀lé ìtàn ìwáṣẹ̀ yìí, a lè sọ pé Odù Ifá ni ó sọ ìtàn Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti bí ó ti ṣe bẹ̀rẹ̀. Bákan náà, bí a bá wo eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ náà lóde òní, a ó rí i pé oríṣìí ẹ̀yà Gẹ̀lẹ̀dẹ́ méjì ló wà. Àkọ́kọ́ ni Tètèdé tí ó jẹ́ abo Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tí àwòrán ìmúra rẹ̀ máa ń ṣe àfihàn obìnrin nígbà tí Ẹ̀fẹ̀ tí ó jẹ́ akọ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń fi àwòrán ìmúra tirẹ̀ hàn gẹ́gẹ́ bí ọkùnrin. Nítorí náà (tọkọ tìyàwó) takọ tabo ni wọ́n jẹ́. Aṣọ àwọn méjèèjì máa ń rẹwà púpọ̀. Èyí ló sì bí gbólóhùn 'ẹni tó bá ti wo Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti rópin ìran ní wíwò'. Ṣé ti ẹwà ni àbí ijó àràmọ̀ǹdà tí ó wà lẹ́sẹ̀ wọn ni kò tó wò ni? Tètèdé fẹ́ràn ijó ẹ̀kà púpọ̀ nígbà tí Ẹ̀fẹ̀ sì fẹ́ràn orin kíkọ tí àwọn ọmọlẹ́yìn rẹ̀ yóò sì máa gbè é.

Ní èrò tiwa, Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ eré Ẹ̀fẹ̀ tí ó bẹ̀rẹ̀ láti Ìlobí ní agbègbè Kétu. Oríkì Ìlobí fi ìdí èyí múlẹ̀. Ìtàn ìwáṣẹ̀ tí a gbọ́ nípa wọn yàtọ̀ sí àhesọ ìtàn náà jẹ́ kí á gbà pé takọ tabo ni wọ́n. Wọ́n máa ń wọ aṣọ aláràbarà tí ó rẹwà láti fi jó. Wọ́n sì máa ń di ṣaworo mọ́ ẹsẹ̀ wọn pẹ̀lú gàrétà gbígbé borí. Ayẹyẹ ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kún fún orin, ìlù àti ijó, ìpohùn tí ó jẹ mọ́ ọfọ̀, àyájọ́, ẹ̀pè àti ẹ̀fẹ̀. Ó sì tún kún fún àwọn ọ̀rọ̀ ìkìlọ̀ àti ìmọ̀ràn tí ó lè mú àyípadà rere bá àwùjọ. Àgbékalẹ̀ eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ láwùjọ dúró lórí ìmọ̀ ìjìnlẹ̀-èrò nípa ìbágbépọ̀ àlàáfíà ẹ̀dá tí ó sọ pé "Ẹ̀sọ̀ layé". Èyí tí ó túmọ̀ sí pé ayé gbẹgẹ́, kí á rọra ṣe, kí á sì gbìyànjú láti gbé ìgbé-ayé pẹ̀lẹ́kùtù. Kí a ṣọ́ra fáyé nípa lílo ọgbọ́n ìfòyegbé, ìrònú-jinlẹ̀, ìbọ̀wọ̀-fún àti ẹ̀mí ìṣọ̀kan láti gbé ìgbé-ayé ìrọ̀rùn láwùjọ.

**Ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti Ìṣàmúlò Ewì rẹ̀ fún Ìmúdúró àti Àyípadà Orílẹ̀-èdè**

Ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti ewì rẹ̀ kún fún iṣẹ́-ọnà, tí ó kún fún ọ̀rọ̀ àwàdà, ẹ̀fẹ̀ ṣíṣe, ọ̀rọ̀ ẹ̀rín, ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti àpapọ̀ orin àti ijó láti dánilárayá. Gbogbo àwọn nǹkan tí a ti dárúkọ lókè wọ̀nyí ni ó wà fún ètò, ìmúdúró àti àyípadà àwùjọ. Ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́, ijó, orin àti àgbékalẹ̀ ewì rẹ̀ kún fún àròjinlẹ̀ Yorùbá tí ó dúró lórí ọ̀rọ̀ ọgbọ́n tí ó sọ pé "Ẹ̀sọ̀ layé". Èyí ni pé kí a fi ọgbọ́n gbé ilé-ayé pẹ̀lú pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ àti ìṣọ́ra. Ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tún fi agbára obìnrin àti bí wọ́n ti ṣe tóbi tó hàn nínú ìṣàkóso orílẹ̀-èdè. Kí àwùjọ máa ka obìnrin sí, ṣe àpọ́nlé fún wọn, tẹ̀lé òfin àwùjọ láti lè fi àwọn obìnrin sí ipò ọ̀wọ̀, kí á bọ̀wọ̀ fún wọn, kí á sì ní àjùmọ̀ṣe papọ̀ pẹ̀lú wọn nínú ètò ọrọ̀-ajé, ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn, ètò òṣèlú àti amúlùúdùn, kí àyípadà rere lè baà bá orílẹ̀-èdè. Àwọn kókó-ọ̀rọ̀ tí a fẹ́ gbé yẹ̀wò lábẹ́ ìsọ̀rí yìí ni ọ̀nà tí ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti ewì rẹ̀ lè gbà yí àwùjọ padà sí rere.

**Ṣíṣe Àpọ́nlé fún Ìyá Wa (Obìnrin)**

Àwọn "Ìyá Wa" túmọ̀ sí àwọn alágbára obìnrin ní àwùjọ ibi tí eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti ń wáyé. Wọ́n sì ní ipa pàtàkì tí wọ́n ń kó ní àwùjọ. Iṣẹ́ ìwádìí tí a ṣe lórí ìṣèré àti ewì rẹ̀ fi àwọn obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí alágbára. Onírúurú àgbàyanu oríkì ni ewì àti orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń lò láti fi àwọn obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí "Ìyá wa", "Ìyàmi", "Éníyán", "Ẹlẹyẹ" tí a tún lè dà pè ní "Àjẹ́". Ní gbogbo àwùjọ tí ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ bá ti ń wáyé, kò sí ẹni tí ó láyà láti pe àwọn obìnrin ní Àjẹ́. Láti pè wọ́n ní àjẹ́ jẹ́ èdè àbùkù àti àfojúdi. Yàtọ̀ sí èyí, ẹni àpọ́nlé ni obìnrin, ó sì yẹ kí á máa yẹ́ wọn sí nítorí ipò àti ààyè tí wọ́n wà ní orílẹ̀-èdè. Ìdí tí àwùjọ fi ń pè wọ́n ní àjẹ́ ni pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan ni wọ́n kó pọ̀. Ní àkọ́kọ́, àwọn ló bí wa kí a tó di ènìyàn. Èkejì, àwọn ni olùtọ́jú ọmọ, olùtọ́jú ilé, ààbò àti olùrànlọ́wọ́ ọkọ. Àwọn ni èjìká tí kò jẹ́ kí ẹ̀wù ó bọ́ sọnù lọ́rùn ọkùnrin. Abájọ tí Drewal (1974:11) fi fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé:

> *If there were no mothers – We would not come into the world… the Great Mother is the owner of everything in the world.*
>
> Tí kò bá sí àwọn ìyá wa – A ò lè wá sí ilé-ayé… Ìyá Ńlá ni ó ni gbogbo ohun tí ó wà ní ilé-ayé.

Àyọlò òkè yìí túmọ̀ sí pé àwọn obìnrin ni Olódùmarè kó ilé-ayé lé lọ́wọ́. Àwọn ni wọ́n ni gbogbo ohun tí Olódùmarè dá nílé ayé. Láìsí wọn, o ṣe-éṣe, kí ẹ̀dá má lè bímọ.

Agbára ìbí tí Olódùmarè gbé lé àwọn obìnrin lọ́wọ́ ni ó mú kí wọ́n lágbára ju ọkùnrin lọ. Nítorí náà, a gbọ́dọ̀ máa ṣe àpọ́nlé wọn kí á sì máa bọ̀wọ̀ fún wọn kí wọ́n lè baà fi gbogbo agbára tí ó bá wà ní ìkáwọ́ wọn tún àwùjọ ṣe kí orílẹ̀-èdè má baà ṣe dojú bolẹ̀. Ìdí nìyí tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kan ní Sábẹ̀ẹ̀ fi sọ pé:

Ìyá mi é é é
Ọlọ́mọ Atáyéṣe
Ìyá mi é é é
Olóde ẹ kú òde
Ọlọ́mọ Atáyéṣe
Olórí ẹyẹ
Olórí ayééé

Níbí yìí, akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ pe àwọn obìnrin ni Ìyàmi, Ọlọ́mọ Atáyéṣe àti Olórí Ayé. Èyí túmọ̀ sí pé àwọn ló layé, àwọn ló lè tún ayé ṣe. Kò sì sí ẹni tí ó lè dí wọn lọ́wọ́ láti má rìn nínú ayé nítorí pé àwọn ni ìyá gbogbo ọmọ ènìyàn tí ó wà lóde ayé. Nítorí náà bí obìnrin bá ń ṣe nǹkan tó dára láwùjọ, kí á má ṣe máa fi ojú aburú wò wọ́n bí kò ṣe kí á máa kí wọn, kì wọ́n ní mẹ́sàn-án mẹ́wàá, yìn wọ́n kí á sì máa gbé òṣùbà ràbàtà fún wọn. Èyí ni yóò mú kí orí wọn yá láti lè fi agbára tí ó wà lọ́wọ́ wọn tún orílẹ̀-èdè wa ṣe.

Àmọ́ ṣá o, àwọn obìnrin lè lo ojú kejì tí wọ́n ní láti lè fi bá àwùjọ jà bí a bá tàbùkù wọn tàbí mú wọn bínú. Ìdí nìyí tí Drewal (1974) fi sọ pé àwọn obìnrin ní agbára rere àti búburú lọ́wọ́. Wọ́n lè bínú láti bá ni jà bẹ́ẹ̀ ni wọ́n sì lè ṣe ni lóore. Èyí fi hàn pé oríṣìí obìnrin méjì ló wà. Obìnrin rere àti obìnrin burúkú tí àwùjọ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń pè ní 'Àjẹ́ funfun àti Àjẹ́ dúdú'. Àwọn obìnrin rere (àjẹ́ funfun) lo agbára tiwọn láti fi tún àwùjọ ṣe nígbà tí àwọn obìnrin burúkú (àjẹ́ dúdú) sì ń ṣe aburú fún àwùjọ. Àti obìnrin rere àti obìnrin burúkú ni Yorùbá máa ń fi oríkì pọ́n lé láti lè wá ojú rere wọn. Ìdí nìyí tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kan ní Ìgànná fi sọ pé:

*Ìyàmi Ọ̀ṣòròǹgà*
*Apani-má-wágún*
*Olókìkí òru*
*Ẹyẹ ńlá abìyẹ́ gbàgìẹ̀-gbàgìẹ̀*
*Òtìtì!*
*Òmìmì!*
*Ẹ̀yin tí Olódùmarè kókùn ilé ayé lé lọ́wọ́*
*Ìyàmi àgbà*
*Ojoojúmọ́ ni mò ń pè yín o*
*Ẹní kí n máa lọ*
*Ẹ ní kò ní ṣòro*
*Ìyàmi àgbà*
*Ẹyẹlé mo mú tòde*
*Ẹ jẹ́ kó yẹ mí o*

Àyọlò òkè yìí láti inú ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fi obìnrin hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó wà nínú awo àjẹ́ ṣùgbọ́n tí wọ́n rí ojú rere Olódùmarè. Ojú rere tí wọ́n rí láti ọ̀dọ̀ Olódùmarè yìí ló mú kí àwọn ọkùnrin náà ó máa bẹ̀ẹ̀rè fún ìrànlọ́wọ́ obìnrin nínú gbogbo ohun tí wọ́n bá ń dáwọ́ lé. Akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ òkè yìí ń fẹ́ kí òde eré yẹ é ló jẹ́ kí ó máa wárí fún wọn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí Olódùmarè gbé àkóso ilé ayé fún tí wọ́n sì tún ní agbára ìbí lọ́wọ́. Ní ìdí èyí, ọkùnrin tí ó bá

ń ṣe àpọ́nlé àti àyẹ́sí obìnrin yóò rí ojú rere obìnrin. Irú àyànmọ́ ẹni bẹ́ẹ̀ yóò tètè wá sí ìmúṣẹ ní kíákíá. Nítorí náà kí á baà lè gbé ìgbé ayé tí ó ní ìtumọ̀, a gbọ́dọ̀ máa gbé oríyìn fún kí á sì máa bu iyì àti ṣe àpọ́nlé obìnrin kí àyípadà rere lè baà dé bá orílẹ̀-èdè. Irú iyì àti ẹ̀yẹ yìí ni ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti ewì rẹ̀ máa ń tẹpẹlẹ mọ́. Bí àpẹẹrẹ, akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìgànná tún tẹ̀ síwájú báyìí pé:

*Ìyá Ńlá*
*Abiamọ tí í fọ́mọ lọ́mú mu*
*Abìdí jẹ̀lẹ̀ńkẹ́*
*Ìyá Ọlọ́mú Òrúbá*
*Abiyamọ abọ̀já gbọ̀ọ̀rọ̀ gbọọrọ*

Àyọlò ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ òkè yìí ṣàpèjúwe obìnrin, "Ìyá wa" gẹ́gẹ́ bí abiyamọ tòòótọ́ tí ó ń fi ọ̀já pọn ọmọ rẹ̀ tí kò fi gbọ́dọ̀ já bọ́, tí ẹsẹ̀ ọmọ kò sì gbọdọ̀ wọ́lẹ̀. Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ yìí ń sọ fún wa pé obìnrin ni ó ń tọ́ ọmọ. Àwọn ló ń ṣe ìtọ́jú ọmọ, tí wọ́n sì ń fún ọmọ ní ọmú. Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ yìí tún ṣe àpèjúwe obìnrin gẹ́gẹ́ bí arẹwà tí ó ní ìdí àti ọyàn tí ó dúróore láti fún ọmọ ìkókó mu. Akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fẹ́ kí àwọn obìnrin máa tọ́jú ọmọ wọn dáadáa, kí wọ́n sì máa fún àwọn ọmọ wọn ní ọyàn tí ó wà ní àyà wọn dáadáa yàtọ̀ sí oúnjẹ ẹranko. Fífún ọmọdé lọ́yàn bí ó ti yẹ yóò mú kí orí ọmọdé ó jí pépé tí àìsàn yóò sì jìnnà sí ọmọ. Ìkéde "ẹ fọ́mọ lọ́yàn, ẹ má gbọyàn lẹ́nu ọmọ oṣù kan" tí ìjọba ń fọ́nrere rẹ̀ náà ni ìmọ̀ràn tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń gba àwùjọ. Ìdí ni pé ọ̀pọ̀ àwọn ìyá ni ó ti kùnà ojúṣe wọn gẹ́gẹ́ bí ìyá láti máa ṣe ìtọ́jú tó péye fún ọmọ wọn. Ìdí nìyí tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fi ń pè fún àyípadà rere fún ìtọ́jú ọmọ lóde òní.



Àwòrán Gẹ̀lẹ̀dẹ́ mẹ́ta, tí wọ́n múra bí obìnrin, wọ́n fi ọ̀já pọn ọmọ ìkókó sẹ́yìn pẹ̀lú ìborùn lọ́rùn. Ọyàn wọn yọ ṣíwájú sọbọlọ. Orísun ìmọ̀: Kétu, ní orílẹ̀-èdè Bìnì.

**Ìbọlá fún àwọn obìnrin**

Ọ̀nà mìíràn tí àwùjọ tún fi lè dàgbà sókè ni kí takọ tabo dìjọ ṣiṣẹ́ papọ̀ fún ìmúdúró àwùjọ. Eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń fìdí èyí múlẹ̀ dáradára. Eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kò fi ojú àbùkù wo obìnrin rárá. Ìdí nìyí tí takọ tabo Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fi wà (Tètèdé àti Ẹ̀fẹ̀). Ọkọ á gbégbá, ìyàwó á gbágbọ̀n ni wọ́n ń ṣe. Bí Ìyáláṣè ti ṣe wà bẹ́ẹ̀ ni Bàbáláṣè náà ṣe wà. Bàbáláṣè kò fojú pa Ìyáláṣè rẹ́. Ìre ni Bàbáláṣè tún ń tọrọ láti ẹnu Ìyáláṣè tí í ṣe obìnrin. Agbára ìtáyéṣe àti àṣẹ ìdáhùn sí ìre tí ọmọ bá wú tàbí èyí tí obìnrin bá wú fún ọkọ, èyí tí ó wà lọ́wọ́ àwọn obìnrin yìí ni akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìgànná fi kì wọ́n báyìí pé:

*Ìyá ò! Mo júbà yín*
*Kí ẹ má jẹ́ kó hun mí*
*Kí ẹ lè mójú tó mi*
*Ìyá ò! bí ẹ bá jẹ́ abiyamọ tòótọ́*
*Ẹ má jẹ́ kó hun mí o*
*Ìyá o! ní gbogbo ọjọ́ ayé*
*Ẹ má padà lẹ́yìn mi o*
*Ẹ bá wa táyé ṣe*

Ìbádọ́gba takọ tabo tí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ dúró lé lórí kò jẹ́ kí àwùjọ fojú àbùkù tàbí ìdọ̀tí wo obìnrin. Abiyamọ tòótọ́ ni àwùjọ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ pe obìnrin. Èyí ló sì fara hàn nínú àyọlò ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ òkè yìí pé ìgbóṣùbà-fún, ìgbóríyìn-fún, ìṣàpọ́nlé-fún àti ìbọ̀wọ̀-fún àwọn obìnrin nìkan ni ó lè mú ìbágbépọ̀ ìrọ̀rùn láàrin ọkùnrin àti obìnrin ó rọrùn. Agbára ìtáyéṣe, ààbò àti àdúrótì tí ó wà lọ́wọ́ àwọn obìnrin yìí ni akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń béèrè fún lọ́wọ́ wọn ní ìlà méjì tó gbẹ̀yìn àyọlò ewì òkè yìí "ẹ má padà lẹ́yìn mi", "ẹ bá wa táyé ṣe". Àwùjọ tí takọ tabo bá ti ń bá ara wọn fọwọ́ sowọ́pọ̀, tí kò sí ìjà òun ìta níbẹ̀, ó di dandan kí àyípadà rere ó dé bá irú àwùjọ bẹ́ẹ̀.

Akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kan ní Sábẹ̀ẹ́ tún tẹ̀ síwájú nínú orin rẹ̀ báyìí pé:

Lílé: *Ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ là ń ṣe*
*Àwa ò bẹ́nìkan jà*
*Bùọ̀dá wa sọ tiẹ̀*
*Àwa kò ṣẹ̀ṣọ́*
*Àwa ò jínigbé*
*Àwa ò pànìyàn*
*Ẹ̀yin aṣèbàjẹ́ ẹ jẹ́ lọ jáwọ́*
*Ẹ yé hùwà tí ò dáa*
*Gẹ̀lẹ̀dẹ́ la fi ń dárayá bíjó bá dé*
*Òtítọ́ la ó ṣe*
*A ò ní purọ́ láéláé*

Ọ̀nà láti lè bu ẹnu àtẹ́ lu ìwà oṣó ṣíṣe, ìgbénipa, ìjínigbé àti ìwà ìpànìyàn tí ó ti gogò sáàrin àwùjọ wa ni akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ gbà gbé ewì rẹ̀ yìí kalẹ̀. Akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lòdì sí àwọn ìwà ìbàjẹ́ wọ̀nyí ó sì kìlọ̀ fún àwọn oníṣẹ́ ibi kí wọ́n lọ so ewé agbéjẹ́ mọ́wọ́. Nítorí náà, eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fàáyè gba àlàáfíà, ìdárayá àti òtítọ́ sísọ. Ó lòdì sí ìjà, ìpànìyàn àti àwọn ìwà aburú mìíràn láwùjọ. Ní ìdí èyí, àyọlò ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ òkè yìí ń pè fún ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti ìwà rere, èyí tí ó lè yí àwùjọ padà sí rere. Akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kan ní Ìmẹ̀kọ tún kìlọ̀ nínú ewì rẹ̀ fún àwọn ọmọ Ìmẹ̀kọ ní ìpínlẹ̀ Ògùn pé:

*Ipẹ̀ là ń ṣe fún yín*

*Obìnrin kì í hurun ẹnu*
*Ọ̀dọ́mọdé ìlú*
*Àgbàlagbà ìlú*
*Ẹ mú sùúrù*
*Ìjà kò dọlà*
*Orúkọ ló ń sọni*
*Ẹ fiyè sórin mi*
*Àlàyé ni mo fẹ́ ṣe fún yín*
*A kò níjà ara ẹni*

Ìjà, ọ̀tẹ̀ òun dúkùú kò lè mú orílẹ̀-èdè tẹ̀ ṣíwájú. Ìdí nìyí tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fi kìlọ̀ fún àwọn ọmọ Ìmẹ̀kọ pé kí wọn ó jáwọ́ nínú ìjà jíjà àti ọ̀tẹ̀ dídì mọ́ra wọn. Ohun tí ó lè mú ìlọsíwájú àti ìyípadà rere bá àwùjọ ni àlàáfíà àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ èyí tí eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ dúró lé lórí.

**Ètò ìlóyún, ọmọ bíbí àti ìwòsàn**

Àgbékalẹ̀ ìṣèré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń mú àyípadà bá ètò ìlóyún, ọmọ bíbí àti ìwòsàn láwùjọ. Bí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà bá fẹ́ kí àyípadà rere bá ètò ìlóyún àti ìwòsàn tó dáńgájíá, ó yẹ kí ó lè ṣe àmúlò àǹfààní ìwòsàn tí ó jẹ jáde nínú ìṣèré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Ìwádìí tí a ṣe ní àwùjọ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fi ògún rẹ̀ gbárí pé àwọn tọkọ taya tí kò bá rọ́mọ bí gbìyànjú láti sún mọ́ àwon "Ìyá wa". Àwọn "Ìyá wa" ni alágbo àti eléwé ọmọ. Ìwádìí tí a ṣe ní Ìmẹ̀kọ fi hàn pé Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lè sọ àgàn di ọlọ́mọ nínú àgbékalẹ̀ ètò eré wọn. Ní gbogbo ìgbà tí àgàn obìnrin bá ń sunkún àìrí ọmọbí, ìwádìí láti ọ̀dọ̀ Ifá lè wá ojútùú sí ìṣòro àìrọ́mọbí fún irú obìnrin bẹ́ẹ̀. Ifá lè sọ pé kí ó lọ ṣe ètùtù sí ojúbọ "Ìyá wa" tí ó dúró gẹ́gẹ́ bí "Ìyá Ńlá" nípa pípèsè aṣọ, gèlè, ọ̀já àti ohun ọ̀ṣọ́ ara obìnrin mìíràn. Ìgbàgbọ́ pé Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lè sọ àgàn di ọlọ́mọ yìí ló so Gẹ̀lẹ̀dẹ́ pọ̀ mọ́ awo abiyamọ.

Nígbà tí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ bá ń jó, àwọn obìnrin tí ó ń wá ọmọ mìíràn lè fún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní ìró, bùbá àti ọ̀já ní ìgbàgbọ́ pé yóò ṣí ojú rere wo àwọn. Nípa ṣíṣe bẹ́ẹ̀, ó lè mú kí ọlẹ̀ ọmọ sọ nínú tí ó bá ń wojú Ọlọ́run fún oyún níní. Bí àpẹẹrẹ, bàbá Alátóto tí ó ti fẹ̀yìntì nínú ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Igán Àlàdé ní agbègbè Kétu ní Ẹ̀gbádò, ní ìpínlẹ̀ Ògùn sọ pé Ifá ló ṣí òun ní iyè láti lọ bọ "Ìyá wa" tí òun fi di ọlọ́mọ láyé ní ọjọ́ òní. Láti ìgbà náà sì ni òun ti ń gbé ìgbé ayé ìrọ̀rùn (Ìbítókun, 1993). Bí a bá wo ọ̀rọ̀ bàbá yìí, a lè sọ pé ọ̀nà ìgbàlà wà nínú Gẹ̀lẹ̀dẹ́.

Àkíyèsí tiwa nínú ètò ìlóyún àti ìbímọ ìgbàlódé ni pé kì í ṣe ilé-ìwòsàn ìgbàlódé nìkan ni ìgbàlà obìnrin wà, pàápàá jù lọ bí obìnrin bá ń wá oyún tí kò sì tètè rí oyún ní, ó lè lo ìlànà ìbílẹ̀ náà láti lè wá ojútùú sí ọ̀rọ̀ ara rẹ̀. Ní òde-òní, onírúurú àwọn ènìyàn ni àìsàn àìmọ̀dí ń ṣe tí ọwọ́ ìṣègùn òyìnbó kò sì kápá rẹ̀. Àwọn ẹlòmíràn kò sì rí ọmọ bí. Ìṣẹ́ ẹlòmíràn kò lọ déédéé. Àwọn ohun tí ó ń fa irú ìṣẹ̀lẹ̀ wọ̀nyí kò yé àwọn dókítà òyìnbó àti àwọn onímọ̀ sáyẹ́ǹsì pẹ̀lú. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni wọn yóò sọ pé kí àwọn aláìsàn wọ̀nyí lọ fi ọwọ́ ilé tò ó. Irú ìlànà ìtọ́jú yìí ni àyípadà ọ̀tun ti dé bá. Àwọn alágbo ọmọ, oníṣègùn ìbílẹ̀ àti àwọn onígẹ̀lẹ̀dẹ́ ti ń gbìyànjú láti wo ọ̀pọ̀ àrùn tí ipá oògùn òyìnbó kò ká sàn ní àwùjọ nípasẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Bí àpẹẹrẹ, abọrẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Ẹ̀gbádò-Kétu kan sọ pé:

> *Àìrọ́mọbí jẹ́ àrùn tí ó pọ̀ jù lóde òní. Ọ̀pọ̀ àwọn tí ó ti lọ sí ilé-ìwòsàn fún ìṣòro àìróyúnní ni wọ́n ti padà wá sí ọ̀dọ̀ wa tí wọ́n sì ń dúpẹ́ lọ́wọ́ Ọlọ́run. A dúpẹ́ lọ́wọ́ "Ìyá wa" tí kò dójú tì wá. Àṣeyọrí tí a ń ṣe ló mú ọ̀pọ̀ àwọn tí ó ní ìṣòro àìrọ́mọbí ó máa wá wo eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lọ́dọọdún. Èyí ló sì ń mú kí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ó máa gbòòrò si.*
>
> (Lawal; Irhue àti Àlíù (2021:97)

Ọ̀rọ̀ tí abọrẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sọ tí Lawal, Irhue àti Àlíù múlò nínú àyọlò òkè yìí fi hàn pé ọpọ́n ètò ìwòsàn ti sún ní òde-òní. Ìlànà ìlóyún àti ìbímọ ti ń gba ọ̀dọ̀ àwọn oníṣègùn òyìnbó kọjá lọ sí ọ̀dọ̀ àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ báyìí pàápàá jùlọ nígbà tí ipá ìṣègùn ìgbàlódé kò bá ká a mọ́. Èyí kò lè jọ wá lójú rárá nítorí pé ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ àti orírun Gẹ̀lẹ̀dẹ́ gan-an dá lé orí ìṣòro àìrọ́mọbí ṣùgbọ́n tí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sì wá ojútùú sí ìṣòro yìí. Nítorí náà, Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti mú àyípadà ọ̀tun bá ètò ìwòsàn, ètò ìlóyún àti ìbímọ ní àwùjọ ní òde-òní. Ìdí ni pé àwọn abọrẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ gbàgbọ́ pé obìnrin tí ó bá ń wá oyún lè ṣe àbẹ̀wò sí ọ̀dọ̀ àwọn kí àwọn sì ṣe ìpèsè oògùn arẹmọ ìbílẹ̀ fún irú obìnrin bẹ́ẹ̀. Bí obìnrin bẹ́ẹ̀ bá fi ìgbàgbọ́ lo oògùn arẹmọ ìbílẹ̀ yìí, ó dájú pé yóò di ọlọ́mọ láyé. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn òṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tún gbàgbọ́ pé, obìnrin tí ó bá ń wá ọmọ lè ra aṣọ tuntun àti ọ̀já fún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lásìkò ọdún, láti lè fi wá ojúrere rẹ̀. Bí ó bá fi ìgbàgbọ́ ṣe èyí, ó lè tìtorí bẹ́ẹ̀ di ọlọ́mọ láyé.

**Ìdàgbàsókè Ìrìn-àjò-afẹ́**

Ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́, orin, ijó àti ewì rẹ̀ ti mú àyípadà bá àwùjọ nípasẹ̀ mímú ìdàgbàsókè bá ètò ìrìn-àjò-afẹ́. Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tí à ń fi ijó rẹ̀ yẹ́ àwọn àgbà sí tẹ́lẹ̀ ti kúrò ní àwùjọ àwọn àgbà, ó ti di eré gbajúgbajà káàkiri àgbáyé. Onírúurú àwọn ẹ̀yà káàkiri orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, ìwọ̀-oòrùn Áfíríkà, Latin Americas, apá kan ní Europe, Australia, àti àwọn ìran ọmọ Odùduwà tí òwò-ẹrú ti kó lọ sí òkè-òkun bí Brazil, Cuba, Venezuela, Germany, Mexico, Haiti, Trinidad àti Tobago ni wọ́n nífẹ̀ẹ́ sí eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn wọ̀nyí ni wọ́n máa ń wá sí orílẹ̀-èdè Nàìjíríà láti wá wo eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lásìkò tí àwùjọ bí Kétu, Ẹ̀gbádò, Èkó, Sábẹ̀ẹ́ àti Ìjió bá ń ṣe ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti di ohun tí Àjọ UNESCO ti tẹ́wọ́gbà ní ọdún (2006) nítorí ìwúlò rẹ̀ ní àwùjọ. Lára àwọn àyípadà tí ìṣèré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ mú bá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà pàápàá ní àwùjọ tí ó ti máa ń wáyé nípasẹ̀ ìran wíwò rẹ̀ àti gbígba ìrìn-àjò-afẹ́ nìwọ̀nyí:

**Gbígbé ọkàn olùwòran fúyẹ́:** Àwọn ènìyàn tí wọ́n bá ní ìpòrúru ọkàn tí wọ́n bá wá wo eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kò ní mọ ìgbà tí àlàáfíà yóò dé bá wọn nípasẹ̀ ìran Gẹ̀lẹ̀dẹ́ wíwò. Yorùbá ní “ènìyàn tí ó bá ti wo Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ti rópin ìran”. Nípa wíwo ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti onírúurú àrà tí ó máa ń fi eré rẹ̀ dá, adùn àti orin ẹ̀fẹ̀ tí wọ́n ń gbọ́ máa ń mú wọn rẹ́rìn-ín àrínlamilójú tí inú wọn yóò sì máa dùn yùngbà. Ní ìdí èyí, eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ máa ń pa ìrònú rẹ́. Ìdùnnú àti ayọ̀ tí wọ́n rí níbẹ̀ yóò mú kí wọ́n tún fẹ́ wá wòran Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní ọdún mìíràn. Ẹni tí inú rẹ̀ bá dùn yóò máa wá ìdàgbàsókè àwùjọ rẹ̀.

**Eré àlàáfíà ni eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́:** Ọkùnrin, obìnrin, ọmọdé àti àgbà ló ń wòran rẹ̀. Àwọn ẹlẹ́sìn Ọmọlẹ́yìn-Jésù àti Mùsùlùmí náà máa ń kópa nínú eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ láìfi ti ẹ̀sìn ṣe rárá. Èròjà ètò ìgbafẹ́ náà ni àlàáfíà àti àmì ìrẹ́pọ̀. Èyí sì máa ń ran ìdàgbàsókè àwùjọ lọ́wọ́. Ìjà kì í wáyé nínú ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Èyí ló sì máa ń fún ọ̀pọ̀ àwọn tí wọ́n bá wá wo eré rẹ̀ lọ́dún tí wọ́n bá ń ṣe é láti lè tún padà ní ọdún mìíràn yálà fún ìdùnnú tí wọ́n rí níbẹ̀ tẹ́lẹ̀ tàbí láti wá fìdí ohun tí ó ń mú àwùjọ dùn tí wọ́n ń gbọ́ nípa rẹ̀ múlẹ̀. Láti fìdí èyí múlẹ̀, akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ kan ní Sábẹ̀ẹ́ kọ ọ́ lórin pé:

Lílé: *Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ò bá ẹnìkan jà*
*Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ò bá ẹnìkan bínú*
*Eré tiwa làwa ń ṣe*
*Àwa ń jó*
*Àwa ń yọ̀*
*Àwa ò bẹ́ni kankan bínú*
*Orin tiwa là wa ń kọ*
*Kiriyó ẹ bá wa jó*
*Mùsùlùmí ẹ bá wa yọ̀*
*Ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ làwa ń ṣe*

Àkíyèsí kókó-ọ̀rọ̀ inú orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ òkè yìí fi eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ hàn gẹ́gẹ́ bí eré tí ó mú àlàáfíà wà láàrin Ọmọlẹ́yìn-Jésù, Mùsùlùmí àti àwọn Ajógẹ̀lẹ̀dẹ́ tí wọ́n dúró fún ẹlẹ́sìn Àbáláyé ní orílẹ̀-èdè.

**Eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́ ọ̀nà láti jẹ ìgbádùn àti ìgbafẹ́:** Bí a bá wo ìṣèré Ẹ̀fẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lásìkò ìṣèré rẹ̀, ọ̀pọ̀ àwọn ènìyàn tí wọ́n wà ní àwùjọ tí wọ́n ti ń ṣe eré rẹ̀ àti àwọn èrò tí ó wá láti ìta máa ń ṣe àmúlò àwọn ohun èlò ìgbàlódé bí wíwọ aṣọ ṣẹ́ẹ̀tì àti túrọ́sà (ọkùnrin), poló àti síkẹ́ẹ̀tì (obìnrin), fífọn fèrè ìgbàlódé àti dídé fìlà bẹntígọ́ọ̀. Àwọn nǹkan wọ̀nyí máa ń mú inú wọn dùn tí wọn yóò sì máa ra ìpápánu bí ẹ̀pà, àgbàdo, awùsá, kókóró, súìtì, bisikíìtì, bọ́ǹsì àti bẹ́ẹ̀ lọ láti fi panu. Lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ àṣekára lọ́dún àti òwò ṣíṣe, àwọn ènìyàn rí àkókò ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ gẹ́gẹ́ bí àkókò ìsinmi díẹ̀ láti tún lè gba okun díẹ̀ sára kí iṣẹ́ ó tó tún bẹ̀rẹ̀ lákọ̀tun.

**Ìdàgbàsókè Ètò Ọrọ̀ ajé**

Eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń mú ìdàgbàsókè bá ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè. Nípasẹ̀ ìṣèré rẹ̀ láwùjọ, orílẹ̀-èdè àti òṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lè máa rí èrè rẹpẹtẹ níbẹ̀. Nípasẹ̀ ètò ìgbafẹ́ àwọn ẹ̀yà mìíràn tí kì í ṣe ìran Yorùbá, àwọn ọmọ Yorùbá tí ó ń gbé ní ilẹ̀ àjẹ̀jì àti àwọn òyìnbó aláwọ̀ funfun tí wọ́n nífẹ̀ẹ́ sí àṣà àti àwọn àjogúnbá Yorùbá lè wá owó sí àpò láti wá wo eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lásìkò ọdún rẹ̀. Èyí sì lè tipasẹ̀ bẹ́ẹ̀ mú kí ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè ó rú gẹ́gẹ́ sí i. Bákan náà àwọn arugi Gẹ̀lẹ̀dẹ́, àwọn aránṣọ Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti àwọn ọ̀kọrin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ pàápàá náà tí wọ́n ti sọ eré yìí di iṣẹ́ yóò máa rí owó gbà láti fi tọ́jú ara àti ẹbí wọn. Èyí fi hàn pé eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń pèsè iṣẹ́ lọ́pọ̀ yanturu fún àwọn ènìyàn tí ó nífẹ̀ẹ́ sí i. Ṣíṣe èyí yóò mú kí ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè yípadà sí rere nítorí pé ètò ọrọ̀-ajé yóò máa rú gọ́gọ́ lásìkò ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Bí àpẹẹrẹ, ọ̀kọrin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìgànná sọ pé:

Lílé/Ègbè: *Ẹ jẹ́ á fẹ̀sọ̀ gbowó*
*Ká fẹ̀gúsí káta rodo*
*Ẹ jẹ́ á fẹ̀sọ̀ gbowó*
*Ká fẹ̀gúsí káta rodo*

Ìtumọ̀ orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ òkè yìí ni pé àwọn akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ò ṣeré lásán, ọ̀nà àtijẹ náà ni eré wọn wà fún. Orísun ọrọ̀ ni eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jẹ́, ìdí nìyí tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìgànná fi tún tẹ̀ síwájú nínú orin rẹ̀ pé:

Lílé/Ègbè: *Mo ló di hé*
*Ó di hé*
*Mo ló di hà*
*Toro-kíto*
*Ẹ ò rí fìlà tí mo rà*
*Ẹ ò rí bàtà tí mo rà*
*Ẹ ò rí aṣọ tí mo rà*
*Toro-kíto.*

Owó tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ rí níbi eré tí ó ṣe ní Ìgànná ló fi ra àwọn fìlà, bàtà àti aṣọ. Èyí sì ni ó fi ń yangàn nínú àyọlò orin rẹ̀ òkè yìí. Ẹ̀wẹ̀ bí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ bá ń kọrin tó mọ́gbọ́n dání tí ó sì mọ oríkì kì dáradára, lójú agbo eré, ó di dandan kí ó rí owó gbà. Nítorí náà bí àwùjọ ti ṣe ń gbọ́ orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tí wọ́n sì ń wo ìṣèré rẹ̀ ló ń ṣe okùnfà owó fun aṣẹ̀dá lítíréṣọ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́, àwọn elégbè, àwọn aránṣọ Gẹ̀lẹ̀dẹ́, àwọn agbé-gàrétà Gẹ̀lẹ̀dẹ́, àwọn agbérẹ́kọ́ọ̀dù orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ jáde àti àwọn tó ń tà á. Gbígbé eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lọ sí òkè-òkun àti gbígbé eré rẹ̀ jáde nínú síídìì (CD) àti díífídìì (DVD) lè mú kí ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè fẹjú sí i.

Ọ̀nà mìíràn tí a tún lè gbà fi eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti ewì rẹ̀ tún ètò ọrọ̀-ajé àwùjọ ṣe ni nípa kí á gba ìṣèré rẹ̀ àti orin rẹ̀ jọ sínú fọ́nrán kí á sì kó wọn sínú ẹ̀rọ ayélujára fún àwọn ènìyàn láti máa fi owó wò ó. Bí àwọn ènìyàn bá ń fi owó wò ó lórí ẹ̀rọ ayélujára, èyí yóò máa mú

kí owó wọlé fún àwọn òṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti orílẹ̀-èdè. Yàtọ̀ sí èyí, àjọṣepọ̀ àwọn olórin àti òṣèré ilẹ̀ òkèèrè lè dìjọ dókoòwò papọ̀ lọ́nà àti lè mọ̀ nípa àṣà orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Bí àpẹẹrẹ Zeynab Abib ní Kútọnu (Cotonou) ní ilẹ̀ Olómìnira Bìnì (Republic of Benin) ti gbé ìṣèré Bọ̀lọ̀jọ̀ àti ijó Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sínú YouTube fún ìgbádùn àwọn ènìyàn tí wọ́n sì ń wò ó pẹ̀lú owó.

**Ẹ̀kọ́ Ìwà Ọmọlúàbí**

Àwọn akadá tí ó ń ṣe iṣẹ́ ìwádìí nípa Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọn lè rí ẹ̀kọ́ pàtàkì kọ́ nípa onírúurú ẹ̀kọ́ ìwà ọmọlúàbí tí ó sodo sínú ewì àti ìṣèré Gẹ̀lẹ̀dẹ́. Lára àwọn ẹ̀kọ́ ìwà tí ó ṣe é mú yangàn tí ó sì lè yí orílẹ̀-èdè padà sí rere ni àwọn ìwà tí Yorùbá lòdì sí bí ìwà olè jíjà, ìjà jíjà, ìkà ṣíṣe, ọtí mímu, ìwà ọ̀lẹ, ìwà ojúkòkòrò, ọ̀tẹ̀ dídì, ìwà irọ́ pípa, ahun ṣíṣe, ìwà ṣìná ṣíṣe àti ara bíbó. Irú àwọn ìwà ìbàjẹ́ wọ̀nyí ni ìṣèré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń bu ẹnu àtẹ́ lù lọ́nà àti lè mú àyípadà dé bá wọn lórílẹ̀-èdè. Bí àpẹẹrẹ, akéwì ìgbàlódé Bọ̀lọ̀jọ́ àti Gẹ̀lẹ̀dẹ́, Zeynab Abib ní Ìsakété/Kútọnu ní orílẹ̀-èdè Bìnì kọ ọ́ lórin báyìí pé:

Lílé: *Tọkọtaya kó máa jà nínú ilé*
*Àṣà yẹn kò wúlò o*
*Ìfẹ́ ló yẹ ká lò kọ́mọ ó lè gbọ́njú bá*
*Ìwà yẹn ó bá dára ló yẹ ká kọ́mọ wa*

Ohun tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń sọ nínú ewì rẹ̀ òkè yìí ni pé kí tọkọ taya ó máa fi ìfẹ́ lò nítorí pé ìjà kò dára. Ẹ̀kọ́ ilé tí a bá fi kọ́ ọmọ náà ló máa múlò nígbà tí ó bá dàgbà. Ẹyin ló ń di àkùkọ. Àwọn ọmọ tí ó bá sì ní ẹ̀kọ́ ilé àti ẹ̀kọ́ ìwé náà ni yóò máa tu ọkọ̀ orílẹ̀-èdè lọ́jọ́ ọ̀la.

Bákan náà, ìṣèré Gẹ̀lẹ̀de àti ewì rẹ̀ wà láti ṣàfihàn ohun tí àwùjọ ń fẹ́ kí ìdàgbàsókè lè dé bá orílẹ̀-èdè. Ọ̀nà tí àyípadà rere fi lè bá orílẹ̀-èdè náà ni kí a máa hùwà rere. Irú àwọn ìwà rere tí ó lè mú àyípadà rere bá orílẹ̀-èdè tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń fọ́nrere rẹ̀ ni ìwà òtítọ́, ìwà ìtẹpámọ́ṣẹ́, àti ìwà rere. Bí àpẹẹrẹ, akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìjió tún kọ ọ́ lórin pé:

Lílé: *Àwa ò purọ́*
*Àwa ò jalè*
*Àwa ò ṣèké*
*Bẹ́ẹ̀ la ò dalẹ̀*
*A ò pànìyàn*
*Òtítọ́ làwa ó máa sọ*
*Irọ́ ò pọ́n wa lé*

Ìwàásù tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń ṣe fún àwùjọ nínú orin rẹ̀ òkè yìí ni pé kí á ṣọ́ra fún irọ́ pípa. Irọ́ pípa, olè jíjà, èké ṣíṣe, ilẹ̀ dídà, ìwà ìpànìyàn kò lè mú orílẹ̀-èdè gòkè àgbà. Nítorí náà òtítọ́ sísọ àti ìfẹ́ àìṣẹ̀tàn ló lè mú orílẹ̀-èdè dàgbà. Bí a bá tẹ̀lé àyọlò ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ òkè yìí, tí a sì ń mú un lò, ó lè yí orílẹ̀-èdè wa padà sí rere nítorí pé òtítọ́ ló ń gbé orílẹ̀-èdè lékè. Ìdí nìyí tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fi tún tẹnu mọ́ ọn nínú orin rẹ̀ pé:

Lílé: *Irọ́ ò pọ́n wa lé ẹ̀yin èèyàn wa*
*Òdodo ló yẹni*
*Bọ́tàá ṣogún ṣọgbọ̀n*
*Òdodo la ó sọ*

Nítorí náà bí a bá ń sọ òdodo tí àwọn alákòóso orílẹ̀-èdè náà sì ń fi òtítọ́ ṣèlú, ó di dandan kí orílẹ̀-èdè yípadà sí rere. Rírọ́ ni irọ́ máa ń rọ́ aláìṣòtítọ́ káàkiri.Lára ẹ̀kọ́ ìwà tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń tẹ̀ mọ́ àwùjọ létí pàápàá àwọn ọmọge òde òní ni pé kí wọn ó ṣọ́ra fún ìwà ṣìná ṣíṣe. Ọ̀pọ̀ àwọn ọmọge òde òní ni ìmúra wọn kò dára. Ìhòòhò ni ọ̀pọ̀ wọn ń rìn. Ara

bíbó ti ba ayé wọn jẹ́. Ọ̀nà láti mú àyípadà bá irú ìwà ìbàjẹ́ yìí ni akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Igbó-ọrà fi ewì rẹ̀ kìlọ̀ báyìí pé:

Lílé: Mo ń kìlọ̀ fún yín o
Ẹ kẹ́tí ẹ gbọ́
Ọmọge alágbèrè
Aṣọ tí kò tólẹ̀ lẹ fi ń ṣòde
Ó ní ẹ sọ pé ẹ kò mọ̀ ọ́n ró
Ró o bòdí nínú yàrá rẹ

Ìmọ̀ràn tí akéwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ń gba àwọn ọmọge òde-òní nínú ewì rẹ̀ ni pé kí wọ́n yàgò fún ìwà ṣìná ṣíṣe, kí wọ́n máa wọ aṣọ tó bo ara wọn, kí wọ́n sì yàgò fún wíwọ aṣọ ìhòòhò lọ sí òde. Bí wọ́n bá fẹ́ lọ sí òde kí wọ́n múra dáadáa gẹ́gẹ́ bí ọmọlúàbí kí wọ́n má ṣe dojú àwùjọ bolẹ̀. Bí àwọn ọmọge ìwòyí bá lè tẹ̀lé ìmọ̀ràn àti ìkìlọ̀ wọ̀nyí, ó dájú pé ìwà ṣìná ṣíṣe àti ìwà ìfipá-báni-lòpọ̀ yóò dínkù láwùjọ.

**Àgbálọgbábọ̀**

Nínú iṣẹ́ yìí, a ti wo ọ̀nà tí eré àti ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ lè gbà mú àyípadà rere bá orílẹ̀-èdè. A wo aáyan àwọn ọ̀mọ̀ràn lórí Gẹ̀lẹ̀dẹ́, ìbẹ̀rẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́, ìṣẹ̀ré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti ọ̀nà tí ìṣàmúlò ewì rẹ̀ lè gbà mú orílẹ̀-èdè dúró tí àyípadà rere yóò sì dé bá a. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé ipa ribiribi ni eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ àti ewì rẹ̀ ń kó nínú ètò ọrọ̀-ajé orílẹ̀-èdè, ìbágbépọ̀ takọ tabo tí ó dán mọ́rán, ìbọ̀wọ̀ fún àwọn obìnrin láti fi agbára wọn ran orílẹ̀-èdè lọ́wọ́, ẹ̀kọ́ ìwà tí ó ṣe é mú yangàn, ètò ìgbafẹ́, ètò ìwòsàn lọ́nà ìbílẹ̀ àti ìbágbépọ̀ àlàáfíà. Àwọn nǹkan tí a mẹ́nubà wọ̀nyí ni ó lè mú ìdàgbàsókè àti ìlọsíwájú bá orílẹ̀-èdè.

Iṣẹ́ yìí wá dá a lábàá pé àwọn ìjọba ìbílẹ̀, ìjọba ìpínlẹ̀ àti gbogbo àdúgbò pẹ̀lú orílẹ̀-èdè bí Nàìjíríà àti Bìnì tí eré àti ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ sábà ti máa ń wáyé gbárùkù ti eré Ẹ̀fẹ̀ Gẹ̀lẹ̀dẹ́, ijó rẹ̀ àti ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ dáadáa lọ́nà tí yóò fi máa pawó wọlé yanturu fún iṣẹ́ ìdàgbàsókè àwùjọ. Ó yẹ kí gbogbo ènìyàn ó gbárùkù ti ọdún àti eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ láìfi ti ẹ̀sìn àti ẹ̀yà ṣe, kí á gbà pé àṣà yàtọ̀ sí ẹ̀sìn, ọ̀kan kò pa ọ̀kan lára. Bákan náà ni kí àwọn ilé-iṣẹ́ ìròyìn máa polongo ọdún Gẹ̀lẹ̀dẹ́ láti máa pe àkíyèsí àwọn ènìyàn sí ọdún rẹ̀ lọ́dọọdún. Èyí yóò sì lè ran ìbágbépọ̀ àlàáfíà lọ́wọ́. Ní ìparí, ó yẹ kí àwọn aṣèwádìí máa kó iṣẹ́ ìwádìí wọn lórí Gẹ̀lẹ̀dẹ́ pàápàá àwòrán Gẹ̀lẹ̀dẹ́, orin àti ijó rẹ̀ sí orí ẹ̀rọ ayélujára fún àwọn ènìyàn láti máa wò kí àṣà àjogúnbá pàtàkì yìí má baà ṣe parun.

**Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí**


Àlàbá, O. (1992). "A Critical Appraisal of the Sub-Classes of Yorùbá Verbal Jokes." In Akínwùmí Ìṣọ̀lá (ed.) *New Findings in Yorùbá Studies*. J.F. Ọdúnjọ Memorial Lectures, Dept. of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn, Ìbàdàn, pp. 149-163.

Aṣíwájú, I.A. (1975). "Ẹ̀fẹ̀ Poetry as a Source for Western Yorùbá History". In Yorùbá Oral Tradition: Poetry in Music, Dance and Drama, Abímbọ́lá, W. (ed.), Ilé-Ifẹ̀, Nigeria, Department of African Languages and Literatures, University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀.

Babátúndé, E.O. (1983). "Kétu Myth and the Status of Woman: A Structural Interpretation of Some Yorùbá Myths". *Journal of the Anthropological Society of Oxford*, 14(3), 301-306.

Beier, H.U. (1958). "Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Masks". *Odù: A Journal of Yorùbá and Related Studies*, 6, 5-23.

Bernolles, J. (1973). "Note sur les, Masques de la société Guẹ̀lẹ̀dẹ́ de Savè (Dahomey Central)". Études Dahomeennes n.s. (numéro special), pp. 23-35.

Dewal, H.J. (1974). "Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Masquerade: Imagery and Motif". *African Arts*. UCLA. James, S. Coleman African Center 7(4), pp. 8-20 (Accessed from www.stor.org/stable.3334883, 20-10-2017).

Drewal, H.J. and Drewal, M.T. (1983). *Gẹ̀lẹ̀dẹ́, Art and Female Power Among the Yorùbá*. Bloomington: Indiana University Press.

Fálẹ́yẹ, A. A. (2009). "Àmúgbòòrò Àṣà àti Ìpohùn Ilẹ̀ Adúláwọ̀ ní Ọ̀rúndún yìí: Ipa Ìpohùn àti Apohùn eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́". *LÁÀŃGBÁSÀ: Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá*, 14, o.i. 94-110.

Fáyọmí, G.O. (1982). "Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìlú Ìmẹ̀kọ – Ẹ̀gbádò-Kétu". B.A. Thesis, Department of African Languages and Literatures, University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀.

Harper, P. (1970). "The Role of Dance in the Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Ceremonies of the Village of Ìjìó. *Odù: A Journal of West African Studies*, 4, Pp. 67-94.

Ìbítókun, B.M. (1981). "Ritual and Entertainment: The Case of Gẹ̀lẹ̀dẹ́ in Ẹ̀gbádò-Kétu". Nigeria Magazine, 136, pp. 55-66.

Ibitokun, B.M. (1993). *Dance as Ritual Drama and Entertainment in the Gẹ̀lẹ̀dẹ́ of Kétu, Yorùbá Sub-group in West Africa*. Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press Ltd.

Johnson, S. (1921). *The History of the Yorubas*. Lagos: CMS (Nig.) Bookshops.

Klein, D.I. (2007). *Yorùbá Bàtá goes Global*. Chicago: The University of Chicago Press.

Koenane, M.J. (2010). "The African Experience of the Forest". Provisionally accepted for Publication". *Southern African Journal of Environmental Education*.

Lawal, B. (1996). *The Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Spectacle: Arts, Gender and Social Harmony*. Seatle: University of Washington Press.

Lawal, B. (1997). "Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Dance Sculpture, Arts for Social Harmony". Unpublished Manuscript, Department of Fine Arts, O.A.U., Ilé-Ifẹ̀.

Lawal, M.O. Irhue, Y.K. and Aliu, N.L. (2021). "Discourse on Ẹ̀fẹ̀ and Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Spectacles in Contemporary Yorùbá Communities in Nigeria". *Annals of the "Constatin Brain cust*" University of targu Jiu Letter and Social Science series (Retrieved from https:alss.utgjiu.ro, 12th August, 2024, pp. 85-100).

Mulero, T. (1970a). "Le Guelede". Unpublished Handwritten Manuscript, Ketu, pp. 1-65.

Mulero, T. (1970b). "Le Guelede au Dahomey". An Unpublished Photo-illustrated Monograph in possession of the Author in Ketu, Dahomey.

Òjó, I.F. (2016). "Àgbéyẹ̀wò Iṣẹ́-ọnà Ajẹméwì àti Ajẹmáwòrán Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Ìjìó àti Sábẹ̀ẹ́" (An Examination of Verbal and Virtual Arts of Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Poetry in Ìjìó and Sábẹ̀ẹ́). M.A. Thesis, Department of African Languages and Literatures, O.A.U, Ilé-Ifẹ̀, Nigeria.

Òjó, I.F. (2017). "Àfihàn Àwọn Ọ̀rọ̀ tó ń lọ láàrin Àwùjọ nínú Iṣẹ́-ọnà Ajẹméwì Gẹ̀lẹ̀dẹ́". *Ẹ̀gin: Jọ́nà Iṣẹ́ Akadá ní Èdè Yorùbá*, 5, pp. 33-62.

Òjó, I.F. (2020). "Ìtúpalẹ̀ Ìmọ̀ Ìjìnlẹ̀-èrò Yorùbá nínú Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ ní Nàìjíríà àti Ilẹ̀ Olómìnira Bìnì" (An Appraisal of Yorùbá Philosophy in Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Poetry in Nigeria and Benin Republic). PhD Thesis, Dept. of African Languages and Literatures, O.A.U., Ilé-Ifẹ̀, Nigeria.

Òjó, I.F. (2021). "Representation of Women Power in Gẹ̀lẹ̀dẹ́ Ritual Performance in Yorùbá Culture". Yorùbá: *Journal of Yorùbá Studies of Nigeria*, Vol. 10, No. 4, pp. 101-124.

Òjó, I.F. (2024). "Ìṣàmúlò Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ bí Ọ̀nà Ìbánisọ̀rọ̀ fún Àtúnṣe Àwùjọ Yorùbá. Nínú Ìlúfóyè F. Òjó, Hakeem Ọláwálé, Taofiq Sa'adu àti Adéwálé L. Ademuyiwa (Ol.), The Voice of the Folklorist: A Festshrift in Honour of Professor George Olúṣọlá Ajíbádé, Ìbàdàn: Bookminds Publishers.

Ọlábímtán, A. (1972). "Gẹ̀lẹ̀dẹ́". *Olókun*, 10, Pp. 37-41.

Ọlátúnjí, C.M.P. and Koenane, M.L.T. (2016). "Philosophy Rumination on Gẹ̀lẹ̀dẹ́: An Ultra-spectacle Performance". *Cultura*. *International Journal of Philosophy of Culture and Axiology* 13(2), pp. 43-51.

Ọlọ́runtọ́, S.B. (2004). "Ẹ̀fẹ̀ and Gẹ̀lẹ̀dẹ́: A Ritual Drama". In Nike, S. Lawal, Mathew, N.O. Sadiku and Adé Dọ̀pámú (eds.), *Understanding Yorùbá Life and Culture*, Asmara, Eritrea: African World Press Inc., pp. 669-677.

Speed, F. (1968). Gẹ̀lẹ̀dẹ́: A Yoruba Masquerade (Colour Film) produced for the Institute of African Studies, University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀, Nigeria.

Tìámíyù, R.O. àti Ọlátáyọ̀, B.A. (2014). "Orin Gẹ̀lẹ̀dẹ́ bí Ohun Èlò fun Ìdàgbàsókè Àwùjọ". *Ìtànṣán Oòduà: Jọ́nà Ẹgbẹ́ Olùkọ́ Èdè Yorùbá Kọ́lẹ́ẹ̀jì Ẹ́ń-Síìì Nàìjíríà*, Fọ́lúùmù Kẹrin, o.i. 191-199.

Willis, J.I. (2018). *Masquerading Politics: Kingship, Gender, and Ethnicity in Yorùbá Town*. Bloomington: Indiana University Press.

Wiredu, K. (2000). "Democracy and Consensus in African Traditional Politics: A plea for a non-partisan democracy P.H. Coetzee and A.P.J. Roux (eds.), *Philosophy from Africa*. Oxford: Oxford University Press, 374-382.

Zeynab Abib (2015). Performing Bọ̀lọ̀jọ̀ and Gẹ̀lẹ̀dẹ́ "Medley". Fekemọ Prod. http://google/y9/Th5. (YouTube, google download on 25/06/2018).

**Compact Disk**

Bàbá Èkó, Ká Ṣiṣẹ́ Ilé (Fọ́nrán), Méré Production.

**Video Compact Disc**

Bàbá Èkó, Ká Ṣiṣẹ́ Ilé (Fíìmù Orin). Méré Production.
Tchabi, T. Fidele, Eré Gẹ̀lẹ̀dẹ́ tí ó ti ká sínú fọ́nrán ní Sarè (Sábẹ̀ẹ́) tí a gbà ní 2017 ní Sábẹ̀ẹ́, Bìnì.

**Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe**

1. Tchabi – T. Fidele, 55yrs, Òkè-Odò, Kingoun-Sarè (Sábẹ̀ẹ́), 25/04/2015.
2. Sàlámì Àlàbí, 79yrs, Ìjìó, 19/07/2015.
3. Òkẹ́ Sàláwù Àkànjí, 72yrs, Ìgànná, 18/07/2015.

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** ÒJÓ, Ilufoye Fawọle. Ìṣàmúlò Eré àti Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fún Àyípadà Àwùjọ àti Àtúnṣe ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p.111-126, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Òjó, Ilufoye Fawọle. (jan./jun.2025).Ìṣàmúlò Eré àti Ewì Gẹ̀lẹ̀dẹ́ fún Àyípadà Àwùjọ àti Àtúnṣe ní Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 111-126.